# AWỌN IṢẸ OLÙṢỌ́

**Isaiah 62:1-7; Esekiẹli 33:1-19; Owe 22:6; 29:15**

**ẸKỌ 369 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Ẹnyin ti nṣe iranti OLUWA, ẹ máṣe dakẹ" (Isaiah 62:6).**

## Ibukun

A gba ọkàn ẹnikẹni ti o ba di Onigbagbọ́ la nitori idi kan ni. Ni tootọ o n fẹ bọ́ kuro labẹ ibinu Ọlọrun, ayọ̀ ọkàn rẹ̀ si ni pe oun n mura silẹ fun Ọrun. O tun ni inudidun pẹlu pe alaafia wà ninu ọkàn rẹ̀ lati igba ti Jesu ti gbe ẹru ẹ̀ṣẹ rẹ̀ lọ. O bu ọlá fun Ọrọ Ọlọrun ni gbigba aanu ti Jesu fi lọ ọ. O si n du u lati gba gbogbo ileri Ọlọrun gbọ́. Gbogbo nnkan wọnyii jẹ iyọri si didi atunbi.

Ṣugbọn igbesi-ayé Onigbagbọ́ tayọ pe a ki a kan maa gbadun awọn ohun ti Ọlọrun fi fun ni. Orin kan sọ pe a bukun wa ki a ba le jẹ ibukun.

**"A bukun mi ki n le jẹ "bukun,**

**A gba mi la lati sin Oluwa Ọba;**

**A fun mi ni 'mọlẹ lati ṣamọna**

**Ọpọ ọkàn miiran wa sọdọ Rẹ."**

Bi a ba ti n sunmọ Jesu si, bẹẹ gẹgẹ ni oungbẹ yoo maa pọ̀ si lọkàn wa to lati sọ fun awọn ẹlomiran pe Jesu fẹran gbogbo eniyan O si n fẹ gba ọkàn ẹlẹṣẹ là. Jesu ni Ọrẹ to dara ju lọ fun wa, o maa n jẹ ẹdun ọkàn wa nigba ti a ba ri awọn ti wọn kọ̀ Ọ.

## Iṣẹ ti a Rán Isaiah

Isaiah fi gbogbo ọkàn rẹ̀ fẹran Ọlọrun. Ni ọjọ kan bi o ti n gbadura ninu Tẹmpili, Ọlọrun ran an ni iṣẹ wi pe ki o lọ waasu fun awọn Ọmọ israẹli ki o si sọ fun awọn eniyan naa niti idajọ ti yoo wá sori wọn bi wọn kò ba ronupiwada. Isaiah kò fi akoko ṣofo rara. Kò ṣe awawi kankan lati maa sọ fun Ọlọrun pe oun ṣi ni awọn nnkan miiran lati ṣe ná. Fun Isaiah, iṣẹ-isin Ọlọrun jẹ ohun ti o tobi ju lọ, gẹgẹ bi o ti yẹ ki o jẹ ohun pataki ju lọ fun gbogbo awọn ti wọn n tọ Ọlọrun lẹyin tootọ.

Fun ọpọlọpọ ọdun ni Isaiah fi otitọ ọkàn sọ fun awọn eniyan wọnyi ohun ti wọn gbọdọ ṣe ki wọn to le wu Ọlọrun. Ni igba pupọ ni awọn eniyan kò fi eti si i. Wọn sa n mookun ninu ẹ̀ṣẹ ṣaa ni. Wọn ṣai bọla fun Ọlọrun ti Isaiah fẹran. O ba Isaiah lọkan jẹ́. Oun kò si le sinmi niwọn igba ti Israẹli kò dẹkun ẹ̀ṣẹ didá ti wọn si n fa idajọ bọ̀ wá sori ara wọn. Iṣẹ ti rẹ̀ ni pe ki o waasu pẹlu ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ agbara Ọlọrun, gbogbo otitọ Ọrọ Ọlọrun ki awọn eniyan ba le ronupiwada, ki Israẹli si di orilẹ-ède nla ti yoo maa fi ogo Ọlọrun hàn ni oju awọn Keferi.

## Titàn fun Jesu

Ọlọrun n fẹ ki awọn eniyan Oun jẹ ibukun fun araye. O n fẹ lati tàn nipasẹ awọn eniyan Rẹ̀, lati fi imọlẹ fun araye. "Lati Sioni wá, pipé ẹwà, Ọlọrun ti tan imọlẹ" (Orin Dafidi 50:2). "Sioni" nipa ti ẹmi ni gbogbo awọn eniyan mimọ́ Ọlọrun, O si n fẹ ki wọn jẹ "pipé ẹwà." Bi iwọ ki ba n gbe igbesi-ayé mimọ́ patapata, o kò ni "ẹwà" rara ni iwaju Ọlọrun. Njẹ ayé tilẹ n ri Jesu ninu rẹ? Imọlẹ rẹ ha n tàn to bẹẹ ti awọn eniyan le fi mọ pe Onigbagbọ ni ọ? Ni igba pupọ ni iṣe wa maa n kokiki wa ju ọ̀rọ ẹnu wa lọ. Iṣe rẹ ha n fi ogo fun Ọlọrun bi? Gba adura agbayọri si Ọlọrun nitori awọn ẹlẹṣẹ. Bẹbẹ fun awọn wọnni ti wọn kò si ninu Ọkọ Igbala.

Wolii Isaiah ni, "Ẹnyin ti nṣe iranti Oluwa, ẹ máṣe dakẹ."

## Awọn Oluṣọ lori Odi

Ni igba lailai, wọn maa n fi odi giga yi awọn ilu nlanla ká ki awọn ogun ọta má ba le wọ inu wọn. Awọn ilẹkun nlanla wà ti a le ti ni igba ti ewu ba n bọ̀. Oluṣọ yoo si lé téntė sori odi naa, lati ibi ti o gbe le ri ọna jijin réré. Oluṣọ ti o ba ṣe oloootọ gbọdọ sọ fun awọn eniyan ilu nigbakuugba ti o ba ri ti abami eniyan n bọ̀ wá, nipa bẹẹ akoko pupọ yoo wà lati ti ilẹkun odi. Nigba miiran oluṣọ a sùn lọ, kò ni le ri

ọta. Tabi bi o ba ri ẹni kan ti n bọ lokeere, o ṣeeṣe ki o ro pe eyi ki i ṣe nnkan ewu kò si ṣanfaani lati kilọ fun awọn eniyan ni ilu rara. A le maa ro pe awọn eniyan gọ̀ pupọ lati fi ilẹkun silẹ ni ṣiṣi niwọn-igba ti wọn mọ pe bi wọn ba ti i ọta ki yoo le wọ ilu.

Ṣugbọn ẹ jẹ ki a ṣe akiyesi bi awọn eniyan ti jẹ alaibikita to lọjọ oni nipa ọta ti o tobi ju lọ, ani Eṣu. O gbọ́n pupọ, o si n du u lọnakọna lati mu ki awọn eniyan lọ si ọrun-apaadi. Nigba miiran oun a ṣe ẹ̀ṣẹ lọṣọ, lati mu awọn ọ̀dọ́ ro pe ki i ṣe nnkan ti o buru lati ṣaigbọnran si awọn obi wọn ki wọn si jade lọ hu iwa ti awọn ọdọmọde ẹlẹṣẹ n hù. O dabi ohun ti o ṣoro fun awọn ọmọ miiran lati mú iduro fun ẹ̀kọ́ ti o tọna. Wọn n fẹ ṣe ohun kan naa ti awọn miiran n ṣe, lai naani yala o tọna tabi kò tọna. Nitori idi eyi ni o fi ṣe danindanin pe ki wọn ni awọn oluṣọ ti yoo maa sọ fun wọn ewu ti ó wà ninu ṣiṣe lodi si awọn ẹ̀kọ́ Bibeli.

Awọn oluṣọ wọnyii jẹ awọn obi wọn, awọn olukọ Ile Ẹkọ Ọjọ Isinmi, ati awọn alufaa ti n waasu fun wọn ni ile isin. Bibeli sọ fun ni pe bi awọn oluṣọ ba ṣe olooot ọ ninu iṣẹ wọn lati maa ṣi awọn eniyan leti nipa iyọrisi ẹ̀ṣẹ, wọn yoo gba ère. Bi awọn wọnni ti o gbọ́ kò ba si gba ìkilọ, wọn yoo jiya.

Bi awọn obi rẹ̀ ba ṣe oloootọ ninu kikọ ọ ni awọn ofin Ọlọrun, ti wọn si n fi ara wọn ṣe apẹẹrẹ iru igbesi-ayé ti Onigbagbọ́ ni lati gbé, ṣugbọn ti o kọ̀ lati gbọran, ìyà rẹ yoo pọ. “Ati ọmọ-ọdọ na, ti o mọ̀ ifẹ oluwa rẹ̀, ti kò si mura silẹ ti kò si ṣe gẹgẹ bi ifẹ rẹ̀, on li a o nà pipọ” (Luku 12:47).

Awọn ọmọ miiran maa n ro pe bi awọn obi wọn ba sa ti jẹ oloootọ, eyi ti to fun igbala ti wọn pẹlu. Ọlọrun n bu ọlá fun iru awọn obi bẹẹ, O si sọ pe: “Tọ́ ọmọde li ọ̀na ti yio tọ̀: nigbati o si dàgba tan, ki yio kuro ninu rẹ̀” (Owe 22:6). Ṣugbọn awọn obi tabi Ọlọrun ti kara Rẹ̀ kò le gba ẹnikẹni la lodi si ifẹ ọkàn ẹni naa. Olukuluku ni lati ronupiwada awọn ẹ̀ṣẹ ti rẹ̀, ki o si bẹ Jesu fun idariji. Nigba ti a ba duro niwaju Ọlọrun fun idajọ, olukuluku ni yoo dahun fun iṣẹ ti rẹ̀, ki yoo si si awawi kankan rara fun ẹnikẹni bi oun kò ba ri igbala.

**Wiwa Lai Lẹṣẹ**

Awọn oluṣọ ti wọn jẹ olukọ Ile-Ẹkọ Ọjọ Isinmi ati awọn ti wọn jẹ alufaa gbọdọ ṣe oloootọ lati fi otitọ Ọrọ Ọlọrun kọ́ ni. Bibeli sọ pe, “Ẹnikẹni ti a bi nipa ti Ọlọrun ki idẹṣẹ” (1 Johannu 5:18), olukọ ti i ṣe oloootọ yoo duro lori odiwọn nì pe Onigbagbọ tootọ ki i dẹṣẹ. Bibeli ni, “A kò le ṣe alaitún nyin bi” (Johannu 3:7). Kò si oloootọ olukọ ti o jẹ sọ fun ọ pe o le lọ si Ọrun nipa kiki didara pọ mọ ijọ kan ati nipa gbigbe igbesi-ayé ti o dara. Bibeli fi ye ni pe nigba ti a ba ri igbala a o di ẹda titun. “Nitorina bi ẹnikẹni ba wà ninu Kristi, o di ẹda titun: ohun atijọ ti kọja lọ; kiyesi i, nwọn si di titun” (2 Kọrinti 5:17). Olukọ ti i ṣe oloootọ yoo sọ fun ọ pe o ni lati ni iyipada ọkàn. Bi kò ba si iyipada ninu ọkàn rẹ nigba ti o ro pe o di Onigbagbọ, o ki i ṣe ọmọlẹyin Jesu tootọ.

Ronu lori ojuṣe ti i ṣe ti gbogbo awọn oluṣọ wọnyi -- awọn obi, awọn olukọ, awọn alufaa, tabi ẹnikẹni ti o le jẹ́ ti o ni aṣẹ lori rẹ. O ni lati yẹ́ wọn si ki o si maa bu ọlá fun awọn ti wọn n sa gbogbo ipá wọn lati ṣe iranwọ fun ọ lati de Ọrun. “Ẹ mã gbọ ti awọn ti nṣe olori nyin, ki ẹ si mã tẹriba fun wọn: nitori nwọn nṣọ ẹṣọ nitori ọkàn nyin, bi awọn ti yio ṣe iṣiro, ki nwọn ki o le fi ayọ̀ ṣe eyi, li aisi ibinujẹ: nitori eyiyi yio jẹ ailere fun nyin” (Heberu 13:17).

**Awọn Alaiṣootọ Oluṣọ**

Ṣugbọn bawo ni yoo ti ri ti oluṣọ kò ba ṣootọ? Ọlọrun sọ pe: “Nigbati emi ba wi fun enia buburu pe, Iwọ enia buburu, kikú ni iwọ o kú, bi iwọ kò ba sọ̀rọ lati kìlọ fun enia buburu na ki o kuro li ọ̀na rẹ̀, enia buburu na yio kú nitori aiṣedẽde rẹ̀, ṣugbọn ẹjẹ rẹ̀ li emi o bere li ọwọ́ rẹ” (Esekiẹli 33:8). Ẹlẹṣẹ naa ki yoo bọ́ lọwọ ijiya nitori oluṣọ kò kilọ fun un, ṣugbọn awọn ti wọn kuna lati kilọ fun un yoo gba idalẹbi niwaju Ọlọrun pẹlu.

**Awọn Ọmọlẹyin Kristi**

Jesu waasu fun ọdun mẹta ati aabọ̀ ninu ayé, O si pada lọ si Ọrun. O fi awọn ọmọlẹyin Rẹ̀ silẹ lati waasu igbala fun araye. A tú Ijọ akọkọ kaakiri ibi gbogbo, wọn si n waasu Ọrọ Ọlọrun.

Fun nnkan bi ẹgbaa ọdun ni a ti n waasu Ihinrere Jesu Kristi, sibẹ o ju idameji awọn olugbe inu ayé ti kò i ti i gbọ́ orukọ Jesu. Pupọ ninu awọn oniwaasu tikara wọn paapaa ni wọn kò ni igbala, bawo ni

wọn ṣe le sọ fun awọn ẹlomiran nipa ibi titun nigba naa? Wọn ki i ṣe oloootọ aloore, bi o tilẹ jẹ pe wọn ni itara. Ẹgbaa ẹ̀ya eniyan ni o wà sibẹ ti kò ni oniwaasù, ẹẹdẹgbẹsan ède si wà ti a kò i ti i tumọ ẹyọ ọ̀rọ Iwe Mimọ́ kankan sí.

Olukuluku eniyan ti a gbala ni o yẹ ki o jẹ aloore fun Ọlọrun. Yoo ha ti ri bi ọ̀kan ninu awọn aladugbo rẹ tabi ọrẹ rẹ ba dide duro ni idajọ ti o si wi pe, "Ẹnikẹni kò sọ fun mi nipa Jesu"? Ọkẹ marun-un eniyan ti wọn n kú lojoojumọ lai gbọ́ nipa orukọ Jesu pẹlu jẹ aladugbo eniyan kan. Jesu kú lati gbà wọn là.

**"Ọkẹ marun-un ọkàn loojọ,**

**N kọja lọ lọkọọkan,**

**Ninu ẹbi ati iwuwo ọkan fun aini Kristi.**

**A! Ijọ Kristi, ki ni oó wi**

**Ni ọjọ idajọ, ọjọ ẹ̀rù,**

**Ti wọn ba sùn ọ́ lẹsun iparun wọn"?**

**Awọn Iranṣẹ Satani**

Awọn eniyan buburu n ṣiṣẹ gidigidi, ni ọsan ati ni oru lati tan ọpọ ọkàn jẹ. Laaarin ọdun mọkanla Ijọba alohun-gbogbo-ṣọkan tankalẹ ni nnkan bi ayika mile mẹrin le ni ogoji ni iṣẹju kọọkan ati nisisiyii o si ti kó o din diẹ ni adọta ọkẹ ni ọna ẹgbẹrun ni ẹrú.

Ki ni ṣe ti ibi tete n gbilẹ ju rere lọ? A ti sọ pe Ijọba alohun-gbogbo-ṣọkan n mú eniyan ni ẹrú o si n fi ipá gba igbọran nipa ẹ̀rù; ṣugbọn Ẹsin igbagbọ́ n sọ eniyan di omnira nipa igbọran ti o ti inu ọkàn ẹni wá si Kristi, o si n fun ni ni igbesi-ayé alaafia ninu ayé, pẹlu iye ainipẹkun. Ikọkọ ni Ẹgbẹ alohun-gbogbo-ṣọkan maa n ṣiṣẹ, ẹmi wọn si wà ninu ewu bi wọn ba kuna. Fun Onigbagbọ́ ni gbogbo anfaani wà fun; Ọlọrun wà ni iha ti rẹ̀. O maa n fi ipin rere fun awọn ti o ṣe oloootọ; Ọrun si n ti ileri kọọkan lẹyin. Awa naa i ba le jẹ oloootọ oluṣọ fun Ọlọrun, ki a maa tan ihin ti o tobi ju lọ ká ayé, ki ọpọlọpọ awọn ti wọn joko si inu okunkun nisisiyii le ri Imọlẹ ki wọn si jẹ igbadun iye ainipẹkun.

**AWỌN IBEERE**

1. Idi wo ni a ṣe gbà wa là?
2. Ki ni Ọlọrun sọ fun Isaiah lati ṣe? Bawo ni Isaiah ṣe dahun?
3. Nitori ki ni awọn oluṣọ fi maa n duro lori odi ilu ni igba lailai?
4. Sọ awọn ọ̀na diẹ ti Satani fi maa n tan awọn ọ̀dọ́ jẹ.
5. Awọn wo ni oluṣọ fun awọn ọmọde?
6. Sọ diẹ ninu awọn nnkan ti oluṣọ ni lati fi kọ́ ni.
7. Ki ni Ọlọrun yoo ṣe fun awọn alaiṣootọ aloore?
8. Ki ni Jesu sọ fun awọn ọmọlẹyin Rẹ̀ lati ṣe lẹyin ti Oun ba lọ?
9. Iye awọn eniyan meloo ni kò i ti i gbọ́ nipa orukọ Jesu?
10. Ta ni yoo sọ ọ fun wọn?